# OLE NPE OLE L'OLE, PARAPARA NBU ENI-ORE

**Ikede**

An Ikede yi fun gbogbo ... Okawe wa ati asoju wa wipe, eni keni ti owo ba teku si owo re ti o tete fi ranse ni... gbogbo ohun elo ti a fi ... irohin lo si gba owo leri.

Enikeni ti ko ba fi tire ranse ... da iwo re duro ao si sa ... lati gba owo wa ni owo re. Olotu


ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

FEDERAL ELECTION

AUGUST 11, 1955

Vote For Adewale

(The boy is good)

VOL. VII No. 425 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA JULY 23 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2d


## Oloye Obafemi Awolowo

LO BA ARA OYO SORO

Aworan iwe wa ose yi koi ti mo. niti eni-Ola Oloye Obafemi Awolowo, okan pataki ninu ojogbon ile Nigeria, ti ise alakoso Ijoba Iwo-orun (Premier, Western Government) ti o lo silu Oyo ninu ose yi,



OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

ti o lo ba awon to nfe ki Oba Alafin pada si Oyo ati awon ti ko fe ki Alafin papa si Oyo soro-oro ti o lo ba t'otun-t'osi won so si wa ni asiri ti enikan koi ti mo.

Awon ti o ko ba soro ni awon ti ko fe ki Alafin pada si Oyo, lehin na ni o tun ba awon to nfe ki Alafin pada si Oyo soro. Nigbati awon Oniwe Irohin de odo re, a gbo wipe Oloye Awolowo so fun won wipe on wa si Oyo nitori alafia ati igbadun Ijoba ni.


LAGOS RACE CLUB

MEMBERS BADGES

Members can now exchange 1954 badges for the new 1955 issue.

Application should be made to the office in the New Tote building.


## Ole Npe Ole L'ole!

Aji epo la npe Ologbo l'abese, ko dede ti a fi p'owe oke wosika wa yi, obinrin ara ilu Abeokuta kan to wa nitosi adugbo wa, o je enia ti Alijonu ti f'owo ba, bi okunrin koja yio so tire si lara, bi obinrin koja yio so tire si lara bakanna.

Nigbati asiwere obinrin kan nkoja ni opopo-ona ti were alaso yi wa, o duro. o nwo iya Egba yi, beni iya Egba so wipe kini iwo asiwere obinrin yi nwo lara mi? obinrin were na si da lohun wipe emi ni were tabi iwo? iwo ti o ko ri owo fi ra atike kun oju re.

Beni, bi o ba ri alapa atike ti iya Egba san mo oju re l'aro ojo na, erin yio pa o; awon mejeji wa bere si bu ara won. A ko tun sese le so orisi isokuso oro to njade l'enu won mo, se iwo an mo oro were.

Ape wo ni gbogbo enia nfi nwon se lojo ti a wi yi, eyi fihan gbangba pe otito ni orin ti awon Akorin Eko ko l'aiye ijoun bayi pe, "Ole npe ole l'ole Aji Epo la npe Ologbo l'abese".

## As'agbe - Jeun Yio Ma Gbawe Ase.

**Katagum** Awon Ijoba Ibile nilu Katagum se ofin ti awon Asagbe - jeun yio fi ma gba Iwe Ase ki nwon to le ma se ise agbe won.

Iwe Ase na pin si ona meji, ekini, Iwe Ase ododun ati ekeji ni Iwe Ase adagba ti ko lo titi de odun kan.

Eni ti ko ba ni Iwe Ase lowo ki o to ma s'agbe yio fi ponun medogbon gbon'ra nu, tabi ki o lo si ewon osu mefa, ti ko ba ri owo san.

Awon ti nwon ka si Asagbe jeun ni awon to ma nki enia l'oriki idile pelu aponle, awon to nfi fere ki enia tabi orin kiko.

No. 73/S. 2/VOL. IV/

## Public Notice

ELECTION TO HOUSE OF REPRESENTATIVES 1955.

By virtue of the powers vested in me under section 12 of Elections (House of Representatives) (Western Region) Regulations, 1954, I hereby declare that in the Oyo Division the following dates are fixed in respect of the new election in Oyo North :-

1. The date of the election shall be 17th August, 1955.
2. All preliminary electoral lists must be published not later than 19th July, 1955.
3. The last day on which claims for inclusion in such preliminary electoral lists, or objections to the inclusion of any name may be made shall be 26th July, 1955.
4. All such preliminary electoral lists shall be finally settled not later than 3rd August, 1955.
5. All nominations for the election shall be made not later than 7th August, 1955, and shall be handed to the Electoral Officer at the New Rest House, Iseyin.

(Sgd.) W. Fowler.
Chief Electoral Officer,
Oyo Province.

Oyo, 1st. July, 1955.


## Aradan Nervigora

Ogun ole pataki fun imarale agba ati aremo pipe fun awon alaya pupo. O da a fun inarun, eje dudu, sokun oju, ogbigbon owo, ailesun, ailokun nnu, ati orisirisi arun bawonni. O je ajideke fun awon ti agbara won ndinku. On na gan ni okunrin yi le ti o fi di "Afese kun bi ojo" 5/-6d pere ni pelu owo oko 1/-6d. o, g. 7/-Post Free.




The Egba Trading Aradan Stores

144, Denton Street, 18, Denton Bridge Street
P, O, Box. 2, Ebute Metta. Phone 41135
a tun wa ni New Motor Park (Ogunpa Ibadan

## Oku Di Meji Ariwo Gb'ojikan

**Ibadan** Ninu ose to koja ni agbayanu jamba Moto kan sele ti enia meta yo s'orun apapa-ndodo.

*Awon* enia mejo ni nwon wo Moto ak'eru kekere kan (Kit-car) ti nwon gbe Posi oku kan sinu re lati ilu Ibadan, ti nwon nlo si Ilu Erunwon ti ko jina ju ibuso meta lo si Ijebu-Ode, lati lo sin oku nibe.

Nigbati nwon rin bi ibuso mejila si Ibadan ni Moto ti nwon wo lo ko sinu koto, nibi koro kan ti a npe ni Idi Ayunren.

Ogbeni Theophilos Ogunbanjo ti ise Oga ile-ise Itewe Kajola ni Ibadan (Manager of Kajola Printing Works) ati omo re obinrin Olufunmilayo l'oku sinu Moto na.

Eniketa to ku pelu sinu Moto na ni Iyafin Victoria Okusanya ti ise iyawo eniti o ni Moto na (Ki-Car No. G84) on si ni awon yoku mba lo sin oku ni Erunwon.


# LAGOS RACE CLUB

## AUGUST MEETING

### SATURDAY 30th JULY, MONDAY 1st AND SATURDAY 6th AUGUST, 1955.

| FIRST DAY | START |
|---|---|
| Race No. 1 Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| Race No. 2 Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| Race No. 3 Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| Race No. 4 Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| Race No. 5 Six Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| Race No. 6 Six Furlongs Handicap Middle Division | 5. 55 p.m. |
| Race No. 7 Seven Furlongs Handicap Top Division | 6. 30 p.m. |

| SECOND DAY | START |
|---|---|
| Race No. 8 Ten Furlongs Handicap Middle Division | 3. 00 p.m. |
| Race No. 9 Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| Race No. 10 Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| Race No. 11 Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 4. 45 p.m. |
| Race No. 12 Ten Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| Race No. 13 Polo Scury | 5. 55 p.m. |
| Race No. 14 Six Furlongs Handicap Top Division | 6. 30 p.m. |

| THIRD DAY | START |
|---|---|
| Race No. 15 Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| Race No. 16 Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| Race No. 17 Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| Race No. 18 Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| Race No. 19 Five Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| Race No. 20 Five Furlongs Handicap Middle Division | 5. 55 p.m. |
| Race No. 21 The Common - Wealth Stakes Ten Furlongs Top Division | 6. 30 p.m. |



**Imoran Fun Enyin Abiyamo**

Enyin abiyamo e ra Omorela O dara pupo fun awon omode

A ma je ki omode ri orun sun daradara, o dara fun otutu iko ati orisirisi arun miran ti o ma nba omode ja ni asiko chin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

**Omorela Baby Mixture**

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN

O wa lodo:

**Commercial Medicine Stores**

QUALIFIED CHEMIST

10, Victoria Street Lagos



**Chairs For Rent**

APPLY

OFE

NO. 3. AIBU STREET LAGOS



**REDIFFUSION**

THE BOX THAT TALKS SINGS & BRINGS MUSIC TO YOUR HOME



Costs less than 3d a day and gives you pleasure for 17 hours.

MAINTAINANCE FREE!

ARE YOU A SUBSCRIBER?

## Enia Meje Segbe

ONITSHA- Qko igi kan ni a gbo wipe o nko ero bo lati Onitsha lo si Asaba, ti o si dojude nitosi Asaba. Awako ati awon ero lo poora sinu omi.
Ni ojo keta ni awon olopa-omi to ri oku awon enia nwonyi.

Anu se wa fun awon ebi oku nwonyi, ki Qlorun se eyi lasomo ki a ma riku omi mo o.


## Dokita Fihan Wipe

### Ose Palmolive Le Jeki Oju Re Dara

LARIN QJQ MERINLA



Ara mi Jolo o tun Jide Nisisiyi ti mo tele ilana ;

Palmolive

Iba ohun ti iwo yio se niyi:-
1 Fi ose Palmolive we oju 2 Fi hiho re pa oju fun iseju kan. 3 Fi aso nu kuro se be nigba meta lojumo fun ojo merinla




EPO ILE AFRIKA

NI A FI SE QSE'YI

COLGATE PALMOLIVE SOAP


## Awon Obinrin Meji Ja De Inu Tubu

**Aba** Awon obinrin Abileko meji kan wa nilu yi ti nwon je osan pelu oru ti nwon ko gbodo f'oju kan ara won. A gbo wipe igbaylowu ti nwon le rin ko ara won lona, a gan yio bere si be.

Nigbati ija' won na di ohun igba gbogbo, owo olopa oba te won Adajo bu owo sisan fun won, ki nwon ye yo alafia ilu lenu.

Koto'jo, kot'osu awon arijagba obinrin wonyi tun pade ara won l'ona, nwon si tun bere ija won. Qlopa oba tun ra won mu, Adajo ni ijogbon ti won to fi opin si nitotina, ki nwon yara lo se osu meji l'ogba ewon bi nwon ba si jade lewon lehin ti nwon ba lo asiko won pari, ki nwon kuro nilu Aba.

Ki l'o nfa ija won igbagbogbo yi wa? enikaniko mo, boya nwon ti pade arawon sinu oko kanna ni, ako mo o.
Qro re, enyin ara wa!

## Qko A Refo o!

Omidan Laster Mosebolatan ti o nse ise nile Ise awon Akowe (Secretariat) ti ise omobinrin bibi inu Qgbeni J. A. Mosebolatan ni enit o lo silu Oyinbo ni ijo kedogun osu July 1955 yi lati lo ko ise Afika-tewe (Typewriter) yekeyeke gegebi a ti gbo

A fi iwe wa yi ki Qgbeni J. A. Mosebolatan atigbogbo ebi re ku ilede, alo yio dara abo yio ni adun bi Oyin. Amin


## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
Medicine Store
7, Egerton Road, Lagos


ALWAYS READ AND ADVERTISE IN ELETI QFE

# ELETI QFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28 Kosoko Street, Lagos "ETI-QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL VII NO. 425 LAGOS SATURDAY JULY 23 1955


## E Yeke Se, Eke Nį Pani

A se wosika wa ose yi niba soki lati fi gba enyin okawe wa ni iyanju lori eke sise. Awon Yoruba l'onpa l'owe wipe "Asofofo ko gba egbaa, ibi ope l'omo." Iwa rere kan ko si ninu atojubo oro oloro, k'ari fenren ki a si ti ma ti enu bole kiri bi igbati elede fi imu bole wa nkan je.

MA JEKI ETI O DI

Ko si ni jeki inu oloware o dun, nitoripe "bi eti ko ba gbo yinkin, inu ko ni baje" ko ye fun omode, ko to si agbalagba, abuku ati irenile ni mu ba ni.

E YEKE SE, EKE NI PANI


***Only Shell's patented I.C.A. gives you ALL the power of the NEW higher octane motor spirit***

# The most powerful motor spirit you can buy

SHELL

WITH

ICA

IGNITION CONTROL ADDITIVE

***Fill up and FEEL THE DIFFERENCE***


No. 92

## NOTICE TO BUILDING, CIVIL ENGINEERING AND ELECTRICAL ENGINEERING CONTRACTORS.

## FEDERAL WORKS REGISTRATION BOARD.

Building, Civil Engineering and Electrical Engineering Contractors are invited to take note of the following procedure which has the approval of the Council of Ministers.

1. Only contractors who are registered in the Federal Works Register of Contractors are eligible to be invited to tender for contracts for Federal Public Works to a value of more than £500.

2. Contractors who wish to be registered in the Federal Works Register of Contractors should complete a Pre-Qualification Form and submit it with their application to the Federal Works Registration Board, P.W.D. Headquarters, Lagos, together with their application for registration. Pre-Qualification Forms may be obtained, on application, from the Secretary of the Board. No fee is chargeable for the Form or for registration.

3. Contractors are requested to state in their applications THE DISTRICTS IN WHICH THEY ARE PREPARED TO UNDERTAKE WORK FOR THE FEDERAL GOVERNMENT. This will facilitate the issuing of invitations to tender.

4. Contractors so registered will be classified into categories according to their capacity. The categories are:-

BUILDING & CIVIL ENGINEERING CONTRACTORS.

| | |
|---|---|
| A. | £501 – £3,000 |
| B. | £3,001 – £6,000 |
| C. | £6,001 – £10,000 |
| D. | £10,001 – £20,000 |
| E. | £20,001 – £50,000 |
| F. | £50,001 – £100,000 |
| G. | Over £100,000. |

ELECTRICAL ENGINEERING CONTRACTORS.

| | |
|---|---|
| A.1. | £501 – £1,500 |
| A.2. | £1,501 – £3,000 |
| B. | £3,001 – £6,000 |
| C. | Over £6,000 |

5. Contractors may be invited to tender for Contracts the value of which is within their own category. They may also be invited to tender for contracts the value of which is within two categories below the category in which they are classified. For Example, a contractor who is classified in Category E may be invited to tender for contracts within the range £6,001 to £50,000. The Minister of works, notwithstanding the foregoing, reserves the right in exceptional circumstances, to invite contractors in the last three categories to tender for contracts in the first four categories of paragraph 4.

6. Contractors may apply for re-classification into a different category after the lapse of a period of twelve months from the date of their previous classification.

7. A contractor who fails to complete a contract will be required to explain the reasons for his failure in writing to the Federal works Registration Board which will consider each case on its merits.

8. If a contractor is unable to produce sufficient justification for his failure, the Federal works Registration Board is empowered to remove his name from the Register.

9. Appeals from the decisions of the Federal works Registration Board will lie in the first instance to the Director of Federal Public Works and then to the Federal Minister of Works.

10. Contractors who wish to be invited to tender for contracts, the value of which is less than £500, should apply to Chief Engineer (Lagos) for registration on the Register of Petty Contractors. Contractors who have been classified by the Federal Works Registration Board in category A or B of paragraph 4 may apply to the Chief Engineer (Lagos) for registration in the Register of Petty Contractors.

J.E.B. HALL,
Acting Director of Commerce & Industries,
Chairman, Federal Works Registrations Board.

## Enyin Amugbo, E Sora

Jimo Abudu ati omode okunrin kan ti oruko re nje Ọlatunde Amosu, to je omo ilewe, ni a gbo wipe Adajo sa konko ponun medogun le lori ni sisan si apo Ijoba tabi ewon osu meji ati koboko mefa pelu, nitori ewe ti nwon npe ni Igbo (Indian Hemp) ti nwon ri lowo won.

Igbo ki ise ohun rere, sinasina ni ise awon to ba mu. E ye'gbo mu.


## Awọn amofin pataki gba pe...

# OVALTINE

*jẹ pataki fun ilera ati agbara*




**ONJẸ MIMU PATAKI**


## Oku Ọlọmo Gege L'a O gbe

IJAGBO-ỌFFA. Alagba Iya oninure, Odewabi Amoke iya Ọgbeni J. A. Tanimowo, Oga Ọladasile ile ise "Agbala Igbadun (The Garden of Eden) ti 139 Griffith Street Ebute Metta l'o jalaisi laipe yi nigbati iya na di eni odun mejileladofa l,ojo ori re li o sinmi saiya Olugbala

Alagba iya wa yi nigba ojo aiye re o je olufokasin ododo ni ile Isin Baptist ni Ijagbo-Offa, o si je onisowo pataki ti Oluwa bukun ise re.

Nigbati Ogbeni Tanimowo de si ibudo oko-ile, Offa (Railway Station) awon opolopo ore ati ojulumo li o wa fi ijo ati ilu ko l'ona, lati ibe ni nwon ti njo lo wole ti ibon ndun lotun-losi larin ilu Ijagbo.

Nigbati o ya lati re iya te si ile ikehin re. Eni-owo Alufa J. L. Boye l'osi isin ikehinti awon opo Alufa miran se isongbe re awon saraki enia l'okunrin lobinrin to peju-pese sibi isinku iya wa yi to egbaji enia. (4000)

Ni ojo ose to tele ti isinku ti a se ijade oku, ki o ma wa gbo bi Alufa ti nsoro lori ise rere re, ese awon olola ati awon enia pataki-pataki ni o pe sibi isin ijade oku Iya wa na.

Awon enia die ti a le daruko niwonyi: Ọba Ọlofa ti ilu Ọffa pelu awon Oloye re, Onijagbo ti ilu Ijagbo pelu awon Oloye re Ọgbeni M.O. Oduba ati iyawo re lati Eko, awon omo-omo oloku ni awon enibi Iyafin Titilayo Fatukasi, Dunmoye Oke: Adegoke Olunlade, Adegboyega Olunlade pelu awon ebi won lati Ede, Ode-Omu, Oshogbo ati Ikirun, pelu Ọgbeni David Asa ti ise aburo J. A. Tanimowo.

Awon Ọgbeni Adesiyan Bello Adeyemo pelu opolopo awon omo Egbe Ibile Ọffa ti Ọgbeni J. A. Tanimowo je alaga fun eka egbe na ti ilu Eko, duro girigiri ti lehin. Sunre, sunre, sunre

## Adelabu Lo Wole

Ibo ti nwon di ni Ibadan ni ojo kokandilogun osu yi fun ati yan enia kan sinu Igbimo oselu Ibadan, Ogbeni Adegoke Adelabu ni ibo mu.




ILE YI LI AWỌN AKEKỌ NGBE NI ZARIA
(INSTITUTE OF ADMINISTRATION)

Ile yi, ti a ko dara-dara je apakan ilosiwaju ninu idagba-soke ile Hausa Simenti oyinbo Burham se iranlowo gidigidi ninu kiko ile na, ati awon ile nla miran kakiri apa Iwo-Orun ile Afrika. Niwon adorin odun sehin, Simenti Burham ti se ranlowo li orisi-risi ona fun ilosiwaju ilu nwonyi. Eyi yi fihan wipe, Simenti tire li o lagbara julo ti a si le gbekele ni gbogbo aiye. Burham Portland Cement

**BURHAM**

PORTLAND CEMENT

## Always Read And Advertise In Eleti Ọfe

**Irora Ehin Didun**

Ọna iwosan rẹ niyi.

Njẹ o mọ wipe Kidinrin lo njẹ ki ẹhin ma dun ọ nia? Bi ko ba si alafia fun nibẹ gbogbo idọti ara ni yio ma se danu Sugbọn bi nwọn bo nṣe tikotikọ idọti ara ti o nwọjọ pọ a ma jẹki ẹhin-dun ni.

Aṣẹ egbogi DE WITT'S PILLS yi lati jẹki Kidinrin siṣẹ. Iṣẹ ti a ṣe egbogi yi fun gan niyẹn, yio wo wọn san tan, yio si mu alafia wa fun oluwa rẹ.

O to iwọn adọta ọdun ti egbogi yi ti nṣe iwosan fun enia ti Ẹhin nro. Aimọye iwe ọpẹ ni a ti si gba kakiri aiye. Lọ ra irẹ ni ṣọbu egbogi.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tan, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo o ra ni sobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**

for Kidney and Bladder Troubles

## QMOLOTO DI OLOMO

*A* gbo wipe, omobinrin kan ti a npe ni Qmoloto nilu Agbara, feran awon omode kekere, a si ma ko won mora, sugbon awon omo ti nwon ba npe ni Aina Kehinde, Ajayi Ige, Taiwo, Alabi, Idogbe, Idowu, Ojo nse li o ma nle won, ti o si ma nna won, ko tile nfe won n sakani odo re.

Lojo kan, obinrin Afin kan ti o bi ibeji, o si je ara Ado Egun, o njo kiri titi, o jo de ojude obinrin ti a npe ni Qmoloto yi. Nigbati obinrin yi jo, jo, jo ti ko fun ni ohunkohun, Obinrin na wipe Howu! Omoloto, awon omo re Ibeji ti nki o lati oni, ese ti iwo ko ta won lore?

Qmoloto dahun wipe "Iya Ajara-buka, iwo li o ma bi meji ti o si ma bi merin". Eyiyi da erin pa Afin na, tobe ti o fi wipe iru oa merin yio ya lodo re.

Loto, loto Moloto ti ko bimo ri ni ojo aiye re l'oyun o si bi omo merin, meji ako, meji abo, sugbon gbogbo nwon je Afin, Ko si ona ti Moloto ko gba tan lati jeki awon omo na di dudu.

Qna ara ni Ise Oluwa.

# Egbogi Ti Colgate Ti A Fi Nfo Ehin Nikansoso Lo Daju Ti O Si Nmu Ireti Wa Fun Opo Enia

## LOSAN ATI ORU KO NJEKI EHIN ENIA BAJE

Lilo ti opo enia nlo egbogi yi fihan wipe egbogi yi ko njeki ehin enia baje pelu egbogi Gardol. Awon Alase isegun ehin ti se ayewo re fun odun kan pe egbogi na ko okuro beni ki nsa. Bi o ba sa ti nlo ni ojojumo, laro ati ni ale, ko ni jeki ehin baje t'osan t'oru.



Sod um N-Laurey: Sncosisalc

S ME RAMILIAR PACKAGE



OKAN NINU AWON OJO-GBON ONISE-GUN EHIN TI SE AYEWO ORO YI.

A ti fi dodo oro yi han nisu iwe ti awon Onisegun ehin te, awon ti gba wipe egbogi ehin ti Colgate pelu Gardol je eyi ti o dara fun ehin to baje ju egbogi miran lo. Nitoripe egbogi Gardol ki njeki ehin baje, lo se jeki awon alase gba wipe egbogi Colgate ati Gardol lo dara julo.




Ko si egbogi ehin kan ti o dara bi eyi.
Ko ni jeki enu re run
Ko si ni jeki ehin re baje.

# O Dara T'osan T'oru Ko Njeki Ehin Eni Baje.


## PWD AND DYNAMOS MEET IN SOCCER TODAY

P W D, the leading team in the League Division I, will this afternoon meet a strong opposition, the DYNAMOS.

This game will no doubt be a tough one. It will be remembered that Dynamos beat SCO A (3-1) in their first match and lost 2-1 in the replay.

Among the players that will be seen in action today are P W.D. - Dovi, Goodluck, George, Okunnu, Williams, Ojehomon, Shyllon, Woma, Ekunsunmi, Enahoro and Sagoe.

DYNAMOS. Olisa, Ekwunob, Dr Sloan, Bobbo, Gbaja, Macgregor, Mutiu and Okafor.

If P W D loses this afternoon's match, then it is evident that RAILWAY will be on stop.

## INTERNATIONAL AHMADIYYA MISSIONARIES CONFERENCE

Maulvi N. M. Naseem Saifi, Amir (Head) & Missionary Incharge of the Ahmadiya Community in Nigeria and Managing Editor of The Truth flew to the United Kindom on the 19th of July to attend the International Ahmadiyya Missionaries Conference to be held in London on the 22nd-24th of July.

The Conference is to be attended by the Missionaries Incharge of the Ahamadiyya Missions in the United States of America, Germany, Holland, Spain, Switzerland, the United Kingdom, British Guiana and Nigeria, and is to be presided over by the Supreme Head of the Ahmadiyya Community, Hazrat M. B. Mahmud Ahmad.

He is expected back in the middle of August.






Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 2337.